# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL. XIV NO 852 LAGOS SATURDAY 5 — JANUARY 11 1 3 KỌBỌ MEJI (2D)


# Oloye Akintola Pada Si Ori Aga Ijoba Re Ni Ibadan, O gba Iyi, O gba Eye Awon Omo Egbe Afenifere Di Alatako

IBADAN—Ggbara ti irohin ti tan kale wipe ofin pajawiri pin ni Ipinlẹ yi ati pe Dokita Majẹkodunmi yio fi ori aga alakoso Ijọba Ipinlẹ na silẹ fun Oloye S. L. Akintọla ti o ti nṣe Olotu Ijọba na ri ni gbogbo awọn enia ti npalẹmọ lọkunrin ati lobinrin lati lọ pade rẹ ni idi ọkọ ofurufu ti o gbe gunlẹ si ni ọna Ọya lati Eko. Oloye Akintọla pẹlu iyawo rẹ ati ọmọ rẹ ti njẹ Mọdele ni nwọn gunlẹ si Ibadan.

Bi ọkọ na ti gunlẹ ni awọn enia jankan—jankan ti o ba wọkọ pọ, awọn bi Ọgbẹni R A. Fani-Kayọde, R Akinyẹmi, Oputa Otutu, Harold Shodipo' awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ pẹlu ọmọ ẹgbẹ Temi Dire, awọn bi Ayọ Roṣiji ati Oloye E O Okunowo jọ̀bọ silẹ ti awọn ti o wa pade won, awọn bi Dokita Ọnabamiro ati N A B Kotoyẹ ti duro dee, nwọn si gba atọwọ tẹsẹ, nwọn si kii ku abọ, gbogbo won si gun mọto ayọkẹlẹ pẹlu rẹ lọ si Agodi nibiti nwọn ti fi Oloye J O Fadahunsi jẹ oye Gomina lọjọ na.

Oloye Akintọla paapa si yan awọn Minisita ti wọn yio ma ba ṣe iṣẹ lọjọ na. Gbogbo awọn Minisita ti o ti wa pẹlu rẹ ti nwọn duro ti i nigba ninu gbodiyan ni o si yan sẹnu iṣẹ pada, ṣugbọn gbogbo awọn Minisita ọmọlẹhin Awolọwọ ba 'gba lọ bamubamu.

Lẹhinti Oloye Akintọla ti de ori aga tan ni o tẹnu bọrọ, o ni on fi tọkan tọkan kesi gbogbo awọn ara Ipinlẹ Iwọ-Orun ki nwọn pa ọrọ ọtẹ ti ki gbogbo wa jọ mu iṣẹ ṣe nitoripe ofin pajawiri ti ba ọpọlọpọ nkan ẹ fun wa. O ni Ijọba on yio mojuto iṣẹ awọn adajọ kotu ibilẹ lati ri pe nwọn ṣe idajọ ododo.

A gbọ irohin wipe awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ ti Ibadan ati agbegbe rẹ ti di ọmọ ẹgbẹ Temi Dire, nwọn ni awọn ko ṣe A G mọ.

---

## Enkuari Pari :

# Adajo Coker Ni Ki Olopa Ba Awon Ti O Lu Ijoba Iwo Orun Ni Jibiti Sejo

Eko—Ni oru ọkanjọ ọjọ aisun ọdun tuntun ni ijẹfa ni awọn Olotu Ijọba Apapọse l'Eko gbe iwe aṣeyọri awọn igbimọ ti o ṣe iwadi pataki lori ọrọ ajọda iṣẹ mẹfa ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti nwọn ti nṣe l'Eko jade fun gbogbo ara ilu. Awọn adajọ Kotu nla Dokita G B A Coker, James O Kassim pẹlu Ọgbẹni Akintọla Williams tiṣe aṣiro-owo ni awọn ti Olotu Ijọba Apapọse yan wipe ki nwọn ṣe iwadi yi.

Awọn oluwadi ọrọ na ninu irohin ti nwọn gbe jade ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori awọn ọmọ gbẹ AG ni o jẹbi ọrọ na nitoripe on ni ẹniti o da ẹgbẹ onisowo kan ti nwọn npe ni National Investment and Properties Coy. Limited ti awọn S. O. Shonibarẹ ati Alfred Rewane nlo ni ọna jibiti lati fi ko ọkẹ aimoye owo si apo ẹgbẹ Action Group; nwọn ni Oloye Akintọla ko ni ọwọ ninu ọrọ na rara. Nwọn tun ṣe alaiye siwaju wipe awọn ri wipe Oloye Awolọwọ ni o yan awọn ọga merin pataki sẹnu iṣẹ owo na, awọn na ni Dokita Akinọla Maja, Alhaji Sule Gbadamọsi, Alfred Rewane ati S O Shonibarẹ.

Ninu iwe akọle ti awọn Olotu Ijọba Apapọse l'Eko kọ le irohin igbimọ iwadi Coker na, nwọn ni ki awọn Ọlọpa'nu ṣe iwadi ọrọ awọn ọga mẹrẹrin ti o ṣe ọga iṣẹ N I P C gbogbo jibiti ti nwọn ba lu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-orun ni ki nwọn ba wọn ṣe ẹjọ le lori, ki nwọn si gba gbese owo ọwọ wọn fun Ijọba Ipinlẹ na.

Nwọn ni owo bi £950,000 tabi jubẹlọ ti nwọn ni awọn sanfun awọn Oyinbo kọlẹ-kọle kan, Cappa and D'Abberto Ltd nigbakan, awọn Oloye Awolọwọ pẹlu Lanlẹhin ati Shonibarẹ ni nwọn ji owo na sapọ ẹgbẹ AG.

## Nwọn Jẹ Lemomu Tuntun Si Mosalasi Durosoto

Ni ọjọ ọsẹ ti o kọja yi ni awọn Janmọ Mọṣalaṣi titun ti nwọn npe ni Mọṣalaṣi Durosoto Alalukurani ni 6, Elias Street l'Eko we lawani fun lemọmu wọn tuntun, Imam Azeez Aro. Alhaji Yesufu Shekoni, Lemọmu agba ti Mọṣalasi Jimọ awọn janmọ Alalukurani pẹlu Lemọmu Mọṣalaṣi Jimọ nla, Alhaji Liadi Ibrahim, ni nwọn we Lawani fun Lemọmu tuntun na, ẹsẹ awọn Alhaji pataki pataki si pe sibẹ.

Alhaji S.A Bakere ni alaga aṣeyẹ ọjọ na, awọn ti o si ṣe isangbe rẹ ni awọn bi Oloye Bada Eko, S B Owokoniran, Alhaji B S Jaji, Alhaji B T Sekoni, Alhaji R A Laguda, Lọya Ade Adewumi, B. Ọlọrunṣogo, S. Agoro Y.O Salawu, M. Ashorobi, B. Ọdunbaku ati L Aiketi pẹlu awọn obinrinn pataki.

Nwọn yin lemọmu tuntun yi ninu iwe-ẹyẹ ti awọn janmọ rẹ fun; nwọn ni awọn ti nṣe akiyesi iwa rẹ lati nkan bi ọdun mẹdọgbọn sẹhin ti o ti nṣe ọmọlẹhin Lemọmu Amode ti Mọsalasi Atini pẹlu lemọmu Mutairu Saheed ni ita Pashi ati pe lemọmu tuntun yi mọ waasi rọ pupọ.

Awọn janmọ Mọsalasi tuntun na tun ṣe alaye ninu iwe ẹyẹ na bi awọn ti ṣe ya kuro ni mọsalasi ti awọn kan ni ẹnikẹni ni ẹbi awọn le fi jẹ lemọmu nitoripe awọn ni awọn ni mọṣalaṣi awọn, nkan ti o si wu awọn ni awọn le ṣenibẹ.

A ki awọn aṣiwaju awọn janmọ na, awọn bi M A Apatira (akọwe) B B Ogunlana. (alaga), I S Matti, L B Ottun (akapo), W A Ottun, M S Dabiri, Y A Oriọla, S Ashesin pẹlu B. Dabiri pe nwọn ku orirere nwọn si ku aṣeyẹ na.



Aworan yi ni ti omidan Susan Platt, ọmọ ilu Gẹsi nibiti o gbe nsọko ṣere nibiti nwọn gb'e lọ ṣere gbogbo agbaiye ni ilu Perth, Australia laipẹ yi. On lo gba iyi lori a nsọko ṣere yi nitoripe oko ti o sọ na rin ẹsẹ bata marunlelọgọjọ o din diẹ; o si gba ẹbun mẹdali oni wura.

## Le Awon Omo Ilewe Ti O Nmu "Igbo" Jade

PORT HARCOURT – Tiṣa agba ile ẹkọ kan ni Pọta (Port-Harcourt) Ogbeni Frank Oki goti orukọ ile-ẹkọ rẹ, njẹ Niger Grammar School ti ha iwefun awọn mejidinladọsan ninu awọn ọmọ ile ẹkọ rẹ wipe ki n'wọn ma tun pada wa si ile ẹkọ na mọ nitori ọrọ buruku ti nwọn nhu.

Irohin ti a gbọ nipa iwe ti awọn ọmọ akẹkọ na nhu ni pe nwon feran lati ma mu ọti kan ti nwọn npe ni „tombo" pẹlu ewe taba "igbo" nṣe ni oju wọn si npọn nigbagbogbo bi ẹṣẹ – ina.


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

INVITATION TO TENDER

1. Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale) during the period 1st January, 1963, to 30th June, 1963, in Apapa Dockyard, Apapa Quays, Customs Quay or any other particular point where the Authority may have scrap metal for disposal in the Lagos or Apapa area.

2. A copy of the tender form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, on payment of a deposit of £5 to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays. The completed tender form should thereafter be returned to the Secretary, in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR SCRAP" so as to reach him not later than Monday, January 14th, 1963.

3. The deposit of £5 will not be refunded in any event to any tenderer who upon being advised of the acceptance of his tender, fails to pay for and to remove the materials made available.

4. Tenderers are warned that scrap available for disposal may comprise both ferrous and non-ferrous materials although it is expected that most of the materials will be ferrous.

5. During the six-month period indicated, the succesful tenderer will be required to remove at his own expense, whatever scrap is made available for sale (with the exception mentioned above) within 7 days of being notified to do so. He will also be required to make necessary arrangements at his expense for all such scrap to be weighed in the presence of a representative of the Authority before being removed.

6. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority.

N.P.A. Notice No. 843
2nd January, 1963.

Gbara ti nwon ti kede wipe Alake Egba, Alaiyeluwa Ladapo Ademola Keji waja ni Abeokuta ni opolopo awon okawe wa lokunrin ati lobinrin ti nso fun Olotu "Eleti-Ole" wipe awon fe ki o se a tun te eda igbesi aiye Oba na ti opitan kan, OMO ABATI ti npa lati iwon nkan bi osu meta sehin. Ni ti gaskia itan igbesi aiye Oba na ti mo OmO ABATI pa fa kikii, ao si te eda meta tabi merin ninu te fun fyin lati se a-tun-gbe-ye-wo bi ilu Egba ti ri ni iwon nkan bi adota odun sehin.

OLOTU

# Kabiyesi Oba Alake Ademola Keji

NWON ni ko si igi meji obi ninu igbo eyi ti ko ba jo o ... ... ... dun ... ni ... Alaiyeluwa Oba Ademola Keji, Alake Egba ti yio di eni adorun odun ni Ojobo (Thursday) ojo marun loni: ti o ba si di ojo mejila a di odun mejilelogoji ti o ti gun ori ite Oba Alake ni Abeokuta.

## Igbaiaiye

Ninu gbogbo igbesi aiye awa omo enia, igba meta ni o je pataki fun wa: sugbon ti Alaiyeluwa Oba wa yi kun fun orisirisi itan ti awon omo kekere yio ri ka lehin wa ola nigbati awon ba nka itan awon oba nla olokiki ti nwon ti je nile wa ri ni apa Iwo Orun Afrika (West Africa).

Ni ilu Abeokuta ni nwon bi Alaiyeluwa Ademola Keji na ni ogunje osu September ni odun 1872: baba re si je oba Alake fun awon Egba niwon nkan bi ogorun odun sehin.

Gegebi mo ti gbo itan na lenu baba ti o bi baba mi Abati Atefate'na, Ladapo ni nwon so Oba na nigbati nwon bii, o si je omo omo Tenidade, omo-Oba Jibodu Oba Alake atijo; Oba Ladapo Ademola yi si tan mo OWU.

Nigba omode re, ile-iwe Ake ti nwon npe ni St. Peter's ni o ko lo ni Abeokuta ki o to wa pari eko re ni Eko ni ile-iwe ti nwon npe ni St's Paul (Breadfruit) leti Olowogbowo.



OBA ADEMOLA KEJI

## Ise L'ogun Ise e

Gbara ti omo-oba ti ko eko re pari, awon obi re ko so wipe se awon je Oba ti o lowo lowo, omo awon le ma se ola kiri, ti o si ma rin kakiri agbaiye ile ise kiko ni nwon ju u si, ti o nsi nko ise awon ti o nte iwe (printer) labe Olotu iwe irohin kan ti nwon npe ni ni "Lagos Observer". oruko Olotu Oga Oba na nje J. B. Benamin.

O se ise na karakara ti o fi de ipo oga awon a-te-iwe (head printer) labe Ogbeni J. P. Jackson, Olotu iwe irohin osose kan ti nwon npe ni "Lagos Weekly Record" nia kan bi odun mejilelogota si igba ti a wa yi. Odun mewa gbako ni Alaiyeluwa se gegebi oga ise ninu ile ite iwe na.

Bi o ti kuro lenu ise atewe yi tan ni awon Ijoba Egba yan ni asoju (ipo eyiti e npe ni Commissioner nisisiyi) won si ilu Eko. Gbogbo igba ti omo oba yi wa l'Eko awon omulumo enia ni o mba rin, o si ngbe ile kan ni Ita Balogun

## Ologboni Kemta

Ninu osun ti nwon yan omo oba Ladapo si ipo Asoju Egba si Eko ni ijongbon nla kan be sile larin awon Ologbo i ad gbo ti nwon npe ni Kemta pelu awon alakoso Ijoba ilu Egba lori a nse idajo lori awon ara adugbo.

Tele-tele ki awon Alakoso Ijoba Egba to da Kotu igbejo sile ni Ake ni iwon ogota odun sehin, awon Ologboni ati Parakoyi ilu Egba ni agbara wa lowo won lati se idajo lori awon arufin ilu ati awon ti nwon ba ko oro won, ko si si agbara ti nwon fi nse eto ilu ti ko si lowo awon ologboni yi.

(Wo yoku loju ewe kefa)

Plushes, Velvet, Velveteen, Damask

& Building Materials

PLEASE CONSULT

Okunowo Brothers

63, Massey Street, Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

# ELETI—OFE

ANJUWON KO ŞE WI LEJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28 Kosoko Street, Lagos, "ELETI—OFE" LAGOS
P O Box 468 Phone 23370

VOL XIV. No. 852 SATURDAY JAN. 5. - JAN. 11. 1962


# E Ku Odun

O dun wa pupọ ti a ko le tẹ ọrọ Olotu wa jade ninu ọsẹ ti o kọja şugbọn ju gbogbo rẹ lọ, a ki enyin ọkawe wa ku alaja ọdun. Olodumare jẹki eyiti a şeşẹ bọ si yi ki o şe gbogbo wa ni rere.

O jẹ aşa gbogbo awọn enia kakiri agbaiye pe ti ọdun ba ti pari ki olukuluku enia gbe oju soke lati gba' dura wipe ki ẹlẹda on gbe ire ko on ati pe ki on maşe pade agbako ninu ọdun tuntun ti on de yi.

Nitotọ o yẹ ki awa ara ilu Nigeria dupẹ lọwọ Ọlọrun ẹlẹda wa pupọ fun ore rẹ lori wa ninu ọdun ti o kọja lọ yi. Şugbọn kinni ipinnu pataki ti olukuluku wa şe fun ọdun tuntun ti a bọ si na?

Ipinnu a o sinmi ọtẹ şişe ni tabi a o mọran ara wa lọwọ ni nkan ti o jẹ pataki ninu alamọri wa ni ilẹ yi ti a ni lati şe fun ilọsiwaju ile wa.

Gbogbo awọn oşelu agbaiye ni nwọn dori kodo lati ro nkan ti nwọn yio şe ki ọrọ ogun ati ọtẹ le kuro ninu alamọri ọrọ wa laiye. Nwọn ni 'agbalagba ki wa lọja ki ori ọmọ-tuntun wọ. Ọrọ rukerudo ti o wa ni gbogbo agbaiye nisisiyi kişe ọrọ awọn agbalagba nikan, gbogbo wa ni a ni lati bọ şokoto ki a kesi ẹlẹda wa ki o fi oju anu rẹ wo wa.

Ifẹ owo ni o gba ọkan gbogbo wa lọmọde lagba, ati gbagbe wipe owo tobi ni ko to enia rara.

Olodumare ki o şe ọdun yi ni ọdun rere fun gbogbo wa o.

## Minisita Obinrin



Aworan yi ni ti Ọlọla Lady Tweedsmuir ti nwọn şeşẹ fi jẹ Minisita tuntun ni ilu Oyinbo laipẹ yi. ọmọ ọdun mẹtadinlogota o si ti wà ni ile igbimọ ilu Oyinbo lati nkan bi ọdun mẹrindinlogun sẹhin, o si ti bi ọmọ mẹta fun bale rẹ.

# Iwe Si Ọlotu

# Awon Aworawo Odun

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ lati bere lọwọ awọn ọkawe yin boya nwọn le sọ idi rẹ ti o fi jẹ wipe awọn Oyinbo ni nwọn mọ irawọ wo pupọ ni aiye.

Mo ra iwe awo-irawọ kan ninu ọdun ti o kọja, gbogbo asọtẹlẹ ti Oyinbo onirawọ na wipe yio şẹlẹ ni o şẹlẹ.

O ni ni ilu wa ni West Africa ede aiyede kan yio bẹ silẹ larin awọn oşelu wa. Bẹna ni o si ri. Akoko ti o sọ wipe jamba a şe awọn ti nwọn ba wọ ọkọ ofurufu ni awọn ọkọ ofurufu bẹrẹsi ja lulẹ.

Bi a ba ri enia dudu ti o le ma so asọtẹlẹ bayi yio dun.

Emi ni,
Eko Babalọla


Advertisement NO. 226.

## Wireless and Television Licences

All owners of wireless an television sets are reminded that the current licences will expire on the 31st December, 1962 and will then require renewal for the year 1963. A licence issued in respect of a residential radio set does not cover a set installed in the licensee's motor vehicle and any person who has a set in both his residence and his motor vehicle requires two separate licences. A wireless licence costs 10/- for a year and a television licence (which covers the use of a wireless as well as a television set) £2:10:-d for a year. These licences may be purchased at all Post Offices and at the larger Postal Agencies.

It is an offence under the wireless Telegraphy Act to operate a set without a licence and offenders are liable to a fine of £50.

The wireless and Television Licence Inspectors of the Ministry of Communications will shortly be undertaking house-to-house inspections of licences. The Ministry is anxious to inconvenience owners of sets as little as possible and it therefore urges them to have their licences readily available for inspection. It should be noted, however, that the Ministry's Inspectors are not authorised to collect licence fees or issue licences.

The Regulations under the Wireless Telegraphy Ordinance require that at the time of purchase of a wireless or televission set the purchaser must produce a valid current licence to the dealer. In their own interest, dealers must insist on this before any sets are given out on sale.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

LATI ỌWỌ AYILUKA

## Akintola Wole

Ki εto bere ọrọ mi ni ọsẹ yi, o yẹ ki oki ọrẹ mi, Oloye Samuel Ladoke Akintọla wipe o ku ajibọ, o si ku ọdun tuntun. Mo gbọ wipe ẹja tuntun ti wọ inu omi, Ijọba Ipinle Iwọ Orun ti di otun. Bẹni, ọrọ Ijọba tuntun yi jẹki nniran orin kan ti a ma nkọ ni aiye atijọ wipe:

Tẹ ba gbọ ti Baba ko le si nkan,
Ko sewu mọ pẹlu iyọnu,
Ija ko si mọ pẹlu ọtẹ,
Tẹ ba gbọ ti Baba ko le si nkan.

Oloye Akintọla, agba d'ọwọ re, ṣugbọn adura emi Ayiluka ni pe ki Olorun tigbomosho ki o pẹlu re, ki o le ba wa gbe Ijọba tuntun na de ibi ti ẹru ko ni ba wa mọ.

## Ifadahunsi

Nwọn ni ibi a ba nsọkun a maa nri ṣan; mo ki Oloye J. O. Fadahunsi, Gomina tuntun Ipinle Iwọ Orun ku orire. Mo ti mọ Ọlọla Oloye Fadahunsi ni Ilesha ti pẹ. Ọmọ Ọwa kii binu ẹru kii binu si binu ọmọ.

Emi Ayiluka paapa mbọ wa ki e ni ipo yi sugbọn ki o ma gbagbe lati fi nkan alejo sile fun rai. Mo fẹ nkan bi oguro ati akara Ijẹsha.

Pẹlu Awe, ori yeye rẹ a gbe ọ, Orisa Ijẹsha a jẹki ẹ ba wa tun ori Ijọba Ipinlẹ wa se. Mo ti o nisisiyi pe Ifa-a daun soro wa. Ifadaunsi.

## Olubadan

Mo ba Ọlọla Ọba Akinyẹle, Olu'baban yọ fun Oye tuntun ti Ọba ilu Oyinbo fi dan lọla ninu ọdun tuntun yi. Nisisiyi Ọba na ti di Sir Isaac Babatọla Akinyẹle Olubadan, Oke Ibadan yio gbe ọ o, Oye na a si mọ'ri o. Kiẹ mafgbagbe emi na ninu adura yin o.


## CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT :

IKORODU TRADING COMPANY

20 & 28 Balogun Street, Lagos.




## Dokita Tuntnn

Aworan ti ẹ nwo yi ni ti Dokita Anton E. Ifekwanigwe ọmọ ile Ibiṣe ria, ti nwọn ṣẹṣẹ fun ni ẹbun n'a kan lati fi kọ ẹkọ si lori bi a ti ṣe lọ̀ ti awọn ọmọde. Oyinbo ti o wa ni apa ọtun re ni Ogbeni Arnold Lucas ẹlẹ̀ ninu awọn ti nwọn fun dokita yi ni ẹbun na.

## Eleti–Ofe D'araba

**E Ku Alaja Odun.**

## Kabiyesi Oba Alake Ademola Keji

(... lati oju ewe ... ẹfa)

### Ndajo Nile

O je inira fun ọpọlọpọ awọn Ologboni awonyi lati fi agbara a ndajọ yi silẹ lẹhinti nwọn d... ofin yi silẹ, ti nwọn si ti fi ... si wipe enikeni ko gbọdọ da ejọ kan labẹ ile rẹ mọ ... awọn onidajọ Kotu Ake. Ṣugbọn Oloye Ologboni Apena Kemta ti o ... nigba na kọ lati ... idajọ ... ile rẹ mọ. O ... idajọ ... awọn Ọlọpa Ẹgba si ... gegẹ ...

Bi ko ba si ... ti Ọba Ladapọ Ademola pẹlu awọn ọmọ Ẹgba ti o nwa ilọsiwaju fun Ijọba igba na ... si ọrọ na ko ba di wipe nwọn nta ẹjẹ awọn ara ilu silẹ lori ọrọ na.

### Reluwe

Ṣaju eyi nigbati Ọba wa yi wa ni ọmọ Ọba ni o ti ba awọn Ẹgba fi egun otolo to ọrọ awọn Ijọba Gẹsi l'Eko lori ọrọ ọkọ-ile ti a npe ni ni Reluwe ti nwọn fẹ mu kọja lori ilẹ awọn Ẹgba.

Nigbati awọn Ẹgba gbọ wipe awọn Ijọba Gẹsi l'Eko (oruko ti Ijọba Nigeria njẹ nigbana ni yi) fẹ mu ọkọ-ile na gba ori ilẹ wọn, nwọn fi aake kọri, nwọn ni awọn ko fẹẹ rara. Ọba Alake yi tun fi ẹsẹ bọ sokoto, o si ba wọn dasi ọrọ na ninu ọdun 1898. Eleyi jẹki awọn oṣelu Ẹgba fi ọwọ si iwe adehun na ti Ijọba Gẹsi l'Eko gbe wa siwaju wọn lori ọkọ reluke yi.





Ninu awọn Aworan meji ti ẹ nwo yi, ẹ o ri ikan nibiti Ọlọla Kashim Ibrahim, Gomina Ipinle Ijọba Ariwa ti ngba Ọlọla Bale ilu Devonshire lọwọ ni ilu Oyinbo ... pelu aṣoju Ijọba Ipinlẹ na, Alhaji Sada Abubakar, ọmọ Ilọrin nigbati Gomina na lọ gba aṣọ oye rẹ ni ilu London.

Aworan keji ni ti Ọba ilu Sweden Alaiyeluwa Gustav nigbati o ngba Dokita Maurice Wilkins ti o gba ẹbun orirere fun iṣẹ ribiribi ti o ṣe lori ki a ma wa egbogi ti ao fi gba awọn ara'ye la. Ẹbun yi jẹ ẹbun pataki ti nwọn ma nfun awọn ogbologbo dokita ti o ba ṣe iṣẹ ribiribi lori a nṣe iwadi egbogi tuntun fun anfani awọn araiye.

E Polowo

Oja Yin Sinu Iwe Irohin Eleti—Ofe Losose

# West African Students Move Into New London University Hostel

LONDON—

Twelve West African students, eight from Nigeria and four from Ghana, are among the first to take up residence in London University's newest hostel which opens its doors next week.

Commonwealth Hall, now nearing completion, will be the most modern of London University's many hostels, with study bed-rooms for 400 students, a library, squash courts, canteen, a billiards room and common rooms.

Two hundred and fifty young men from all over the world will be moving into the hostel next week, including some post-graduate research students. With the West Africans will be students from India, Pakistan, America, Canada, Cuba, Germany and the Soviet Union.

"Commonwealth Hall is not planned only for students from overseas but we shall try to keep a balance between the different countries represented and also the different colleges at which they are studying," said a member of the staff.

"All the rooms will not be completed immediately but when the building is coumpleted we hope it will go a long way towards alleviating the accommodation problem for students in London".

## New Apointment For Sir Philip Rogers

LAGOS—Sir Philip Rogres, one of the first two commercial members of the postwar Nigeria Legislative Council will shortly take up a new appointment as Chairman of the Tobacco Manufacturers Standing Committee in the United Kingdom.

Sir Philip, who for the past 11 years has been Chairman of East African Tobacco Company Limited spent 18 years in Nigeria in the tobacco industry.

As Factory Manager he established Nigeria's first experimental cigarette factory in a disused cotton ginnery at Oshogbo in 1935. Two years later he took charge of the then British American Tobacco Company's (now Nigerian Tobacco Company's) new cigarette factory at Ibadan.

He was President of the of the Lagos Chamber of Commerce in 1948 and 1950 and from 1947 to 1951 served as a member of the Legislative Council.

## University Opens Centre For Africans



SCOTLAND—
Two Nigerians look at newspapers in the library of the new Centre of African Studies which will be officially opened at Edinburgh University, Scotland this mouth. On the left is Mrs. Rose Osuji from the Ministry of Finance, Enugu, Nigeria. Her companion is Miss Olayinka Alimi, of Ondo Western Nigeria.

The libary will eventually include many rare 18th- and 16th-century volumes and papers and a record of impor tant material in other Scottish libraries will be prepared

The centre, which will be offically opened by Lord Hailey will provide research facilities for British and African graduates. A post-graduate diploma will be introduce for workers who "wish to supplement their existing degree by a wider and more integrated knowledge of Africa affairs".

## Purchase Tax Cuts In Britain

London—British purchace tax of 45 per cent on various consumer goods has been cut to 25 per cent, as from yesterday, the British Chancellor of the Exchequer Mr. Reginald Maudling has announced in London.

The new measure will have the effect of stimulating production and exports.

Items affected are mainly television and wireless sets, gramophones, perfumery and cosmetics. Now there will be only three rates of purchase tax, the standard rate of 25 per cent and the two lower rates of 15 and 10 per cent.

In his announcement, the Chancellor said that the recent reduction in the purchase tax on motor cars from 45 to 25 per cent was made in recognition of the importance of the industry to exports, investment and to the economy generally, and he did not now consider there was any justification for continuing the exceptionally high level of 45 per cent on remaining items such as television sets etc.

# Oloye Ojikutu Mba Itan Rè Lo Lori Awon Alapata

"Ni ọsẹ ti o kọja, mo ni a ngba oromọ-adiẹ lọwọ iku ati ọrọ awọn ọlọtẹ diẹ ninu awọn alapata ẹran l'Eko ti nwọn ni awọn rọ emi Oloye Abudu Yekinni Ojikutu loye Baba ẹgbẹ ati pe ki emi to jade ni ile iwe ni awọn ti da ẹgbẹ alapata ẹran sile nilẹ yi. Mo ni irọ ni nwọn fi eyi pa, mo si ti nsọ itan bi ẹnikẹkan awọn ọlotẹ na ṣe di alapata ẹran sinu iwe yi lati bi oṣu kan wa.

"Alangba ti o fẹ fi jigi soju ni ọrọ awọn ọlọtẹ alapata na, ṣe ogiri lasan ni yio fi jigi na wo ! Beni ẹrọ Shittu Allao, ọkan ninu wọn ti a ma n pe ni Shittu Oloorun ni ọjọ yẹn lọhun ri ṣugbọn o ti di Alhadji Shittu nisisiyi.

"O to ọdun mẹdọgbọn nisisiyi ti emi Oloye Ojikutu gba a ni ọmọ iṣẹ fun iya iyawo mi, Ọlatẹju Atunwa, ti mo si mu u lọ siwaju alaṣẹ imọtoto ilu Eko (Medical Officer of Health) Dokita Ajọṣẹ ti o ni Ibadan nisisiyi wipe on ni ọga iṣẹ labẹ ana mi na.

"O jẹ aṣa fun awa alapata bi ẹnikan ba jalaisi ninu wa, ti o ni ara lọmọ, laburo, lọkọ tabi laya ti o nta ẹran, on ni nwọn ni lati gbe iṣe isọ rẹ fun. Iyawo mi si nta ẹran titi di ọjọ oni, ṣugbọn sibẹsibẹ Shittu Oloorun yi ni o jogun iṣẹ ana mi dipo ki nwọn fun iyawo mi tiṣe ọmọ ẹnikosi Atunwa. Nwọ[n] ni nitoripe mo ti mu wa si iwaju awọn. Eni na k[...] si binu si i. O wa tọ ki Shittu Alao gba isọ iy[...] iyawo mi nitoripe a ṣe lanu ? Ikan niyi ninu ọr[...] awọn a fi ibi ṣu olore na o ! ọdun mẹfa gbako ni [...] fi ṣe iṣẹ lebira labẹ ana mi.

"A ti mọ wipe alakan ti o ba da'gi mu a fi k[...] o re iga ni ọrọ ti Alufa Alabi ti ọrọ wa yi kan n[...] sisiyi ti o wa di Alhaji loni. Ọkunrin kan ti a np[...] ni JATO ni ọga ọmọṣẹ odo fun Amọdu Rufai Ọlo[...] runkọjẹ. A ti suke ko sẹhin lakuroẹbe, ki Alufa Alab[...] yi to di ọmọṣẹ labẹ JATO yi. O mba wọn fa oku[...] ẹran malu lọ sodo, o si tun mba wọn kun ẹran lod[...] lọjọ na lọhun.

"Nigbati iyawo Ọlọrunojẹ ti o jẹ ẹgbọn Aluf[...] Alabi yi nṣe aroye wipe ẹgbọ. on ko ri ikan ṣe ka[...] ni awọn baba ti nwọn fi mi jẹ olori alapata ba b[...] mi sọ, ni on na ba fi di Alapata labẹ ọpagun em[...] Ojikutu lati nkan ọdun mẹdọgbọn sẹhin nitoripe on [...] a-kun-ẹran lodo ni i ṣe labẹ Ọgbẹni Jato.

"Iyoku di ọsẹ ti mbọ nitoripe aye ko si pupọ lọsẹ yi.


## A Unique New Year Present From FIAT

F I A T

### 12 MONTHS OR
### 12,000 MILES
# GUARANTEE !!!



Fiat, confident about the higher quality of their products are proud to offer this exceptional guarantee for cars purchsed after 1st January, 1963.

DRIVE MORE ECONOMICALLY AND SAFELY IN 1963 IN A FIAT, THE CAR BACKED BY AN OLD TRADITION AND UNMATCHED GUARANTEE.

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (EB) . IBADAN . KANO . JOS . KADUNA . PORT HARCOURT . ABA

G U A R A N T E E


Printed and Published by Sue Calon Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 EDITOR (CLOTU) ỌLA ONATADE